# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ̀

## FÍFÚN ILẸ̀ NÍ ÌSINMI

## Ìtàn ...

**2 Kronika 36:11-21**

Nigbati a kọ́kọ́ da ayé, a da ohun gbogbo ni pípé. Ènìyàn, ẹranko, ati ohun ọgbin gbogbo wà ni alaafia laisi wàhálà kankan. Ṣugbọ̀n ni kété ti ẹ̀ṣẹ̀ wọle, ohun gbogbo yípadà. Awọn ènìyàn bẹ̀rẹ̀ si ni jẹ ẹranko, awọn ẹranko pẹlu njẹ ara wọn. Ẹgun ati oṣuṣu nhù jade nibi gbogbo. Ìjìyà ẹ̀ṣẹ̀ tu mú èròjà tó wà ninu iyẹ̀pẹ̀ dínkù. Ọlọrun sọ fun Kaini pé "Nigbatí iwọ ba ro ilẹ, lati isinsinyi lọ, ki yio fi agbara rẹ̀ so èso fun ọ mọ́." Genesisi 4:12.

Eleyi ni ìdí ti Oluwa fi pàṣẹ ki awọn ọmọ Israeli fun ilẹ̀ wọn ni isinmi ni ọdun meje meje (Eksodu 23:10,11).



Èyí yio fun àwọn ilẹ̀ náà ni ànfàní lati gba okun ati agbára lati so èso fún awọn táláka lati jẹ. Ṣùgbọ́n ọpọlọpọ awọn ènìyàn Ọlọrun ló gbàgbé àṣẹ yi tabi ti wọn kọ̀ lati pa òfin yi mọ́. Nígbàtí o di ọjọ́ kan, ìdájọ́tikòdẹrùndé, Nebukadnessari, ọba Babiloni wá sí Juda lati ṣe ìdájọ́ awọn ti wọn sọ̀tẹ̀ si i ati lati pa wọn, o si kó awọn íyókù lọ si ilu Babiloni. Lojukanna, ilẹ̀ Israeli di fifi silẹ ni ahoro ni idakẹ́jẹ́, títí wọn fi “san ọdun isinmu rẹ̀, ani ni gbogbo ọjọ́ idahoro oun nṣe isinmi.” 2 Kronika 36:21. Ni òpin aadọrin ọdun, awọn to kù padà wa sí Kenani lati tún Jerusalẹmu kọ́ ati lati gbin awọn ohun ọ̀gbìn wọn padà ni ilẹ̀ ìlérí.

Fún ìwọ̀n ẹgbẹrun mẹfa ọdun bayi, Jesu ti ngbin eṣo ihinrere. Bibeli sọ fun wa pé, “ọjọ́ kan lọ́dọ̀ Oluwa bi ẹgbẹrun ọdun li o ri.” 2 Peteru 3:8. Láìpẹ́, Jesu Ọba yio wa kórè ayé. Ọ̀pọ̀ yíò kú nipaṣẹ̀ ìtànsán ogo rẹ bo ti nbọ̀, a o si ko awọn iyokù lọ si ijọba Rẹ̀ tí a fi wúrà kọ́. Nigba náà ni ilẹ̀ ayé gbígbó ti o si ti rẹ̀ yio sinmi fun ẹgbẹrun ọdun.

# Ẹ̀kọ́

Di àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

**1.** Awọn ìṣẹ̀lẹ̀ wo lo ṣe àmì ìbẹ̀rẹ̀ ẹgbẹ̀rún ọdun náà?

**1 Tessalonika 4:16**
Nitori _____ tikararẹ̀ yio_____ lati ọrun wá ti oun ti ariwo, pẹlu ohùn olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn òkú ninu Kristi ni yio si kọ́ _____.
**Ifihan 20:4,5**
Mo si ri awọn ìtẹ́, nwọn si joko lori wọn, a si fi idajọ fun wọn: mo si ri ọkàn awọn ti a ti bẹ́ lori nitori ẹri Jesu, ati nitori ọ̀rọ̀ Ọlọrun, ati awọn ti kò si foribalẹ fun ẹranko naa, ati fun aworan rẹ̀, tabi ti kò si gbà àmì rẹ̀ ni iwaju wọn ati li ọwọ́ wọn; nwọn si wà laaye, nwọn si jọba pẹlu Kristi li _____ ọdún, Awọn òkú iyokù kò wà laaye mọ́ titi ẹgbẹ̀rún ọdún naa yio fi pé. Eyi li ajinde _______.

Àkíyèsí: Ẹgbẹrun ọdun ti ìwé Ifihan ori ogun ni a saba ma n pe ni milẹniomu. Milẹniomu jẹ́ ọ̀rọ̀ lati inu èdè Latini tí o ni ọ̀rọ̀ meji nínú: "mil," túmọ̀ sí "ẹgbẹ̀run" ati "ẹniomu" túmọ̀ sí "ọdún." Ipadabọ̀ Jesu ati ajinde awọn olododo jẹ́ ìbẹ̀rẹ̀ ẹgbẹ̀rún ọdún náà. Awọn ènìyàn mímọ́ oniruuru ọjọ́ ori ( ti a pe ni "Olubukun ati mímọ́" ni ẹsẹ kẹfa) ni a o ji dide ni ajinde ekinni.

**2.** Kilo tún kù ti yio ṣẹlẹ̀ ni ajinde ekinni ?

**1 Korinti 15:51,52**
Kiyesi i, ohun ijinlẹ ni mo sọ fun nyin; gbogbo wa kì yio sùn, ṣùgbọ́n gbobgo wa li a o __________, Lọ́gán, ni iṣẹ́jú, nigba ìpè ikẹ̀hìn: nitori ipè yio dún, a o si jí awọn okú dide li aidibajẹ́ a ó si pa wa lára dà.
**Filippi 3:21**
Ẹnití yio sọ ara ìrẹ̀lẹ̀ wa di ọ̀tun ki o le bá ara _______ rẹ̀ mu, gẹ́gẹ́ bi iṣẹ-agbára nipasẹ̀ eyiti oun le fi tẹ ori ohun gbogbo ba fun ara rẹ̀.
**2 Tessalonika 2:8**
Nigbana li a ó si fi Ẹni ẹ̀ṣẹ̀ nì hàn, ẹniti Oluwa yio fi eemi ẹnu rẹ̀ pa, ti yio si fi ifihan wíwá rẹ̀ sọ di _______.
**Ifihan 16:18,20,21**
Mànamána si kọ, a si gbọ́ ohùn, àrá si sán, _______ nlá si sẹ̀, irú eyití kò sẹ̀ rí lati igbatí enìyàn ti wà lori ilẹ̀, irú ìsẹ̀lẹ̀ nlá bẹ́ẹ̀, ti o si lagbara tobẹ́ẹ̀, Olukuluku erekuṣu si salọ, a kò si ri awọn òkè nlá mọ́, _______ nlá, ti ọkọ̀ọkan rẹ̀ tó talẹnti ni ìwọ̀n, si bọ́ lu awọn ènìyàn lati ọrun wá: awọn ènìyàn si sọ̀rọ̀-òdì sí Ọlọrun nitori iyọnu yinyín naa; nitori ti iyọnu rẹ̀ náà pọ̀ gidigidi.
**Ifihan 20:1,2**
Mo si ri angẹli kan nti ọrun sọkalẹ̀ wá, ti oun ti ìṣika ọgbun ni, ati ẹ̀wọ̀n nlá kan li ọwọ́ rẹ̀, O si di dragoni náà mú, ejò atijọ́ nì, ti iṣe Eṣu, ati Satani, o si _____ e li ẹgbẹ̀rún ọdún.

Àkíyèsí: Lọ wo aworan ẹgbẹ̀rún ọdún naa ni ojú ewé keje fun awọn ohun ti yio ṣẹlẹ̀ ni kúkurú, ni kété ti ẹgbẹ̀rún ọdún náà bati bẹ̀rẹ̀.

**3.** Awọn wo ni a o jí dide ni ajinde keji, ìgbà wo ni yio ṣẹlẹ̀ ?

**Johannu 5:28,29**
Ki èyí ki o máṣe yà nyin li ẹnu; nitori pé wakati mbọ̀, ninu eyiti gbogbo awọn ti o wà ni isà òkú yio gbọ́ ohùn rẹ̀, Nwọn o si jade wá; awọn ti o se ______, si ajinde ìyè; awọn ti o si ṣe buburu, si ajinde _______.
**Ifihan 20:5**
Awọn òkú iyokù kò wà laaye mọ́ titi ẹgbẹ̀rún ọdún naa yio fi ____. Eyi li ajinde ekinni.

Àkíyèsí: Awọn ẹni buburu ni a o ji dide ni ẹkeji ni ajinde gbogbo eniyàn, ni òpin ẹgbẹrun ọdún náà.

**4.** Kinni ipò ayé ni ìgbà ẹgbẹ̀rún ọdún náà?

**Isaiah 24:1**
Kiyesi i, OLUWA sọ ayé di _____, o si sọ ọ di ahoro, o si yi i po, o si tú awọn olùgbé inu rẹ̀ ká.
**Jeremiah 4:23-26**
Mo bojuwo ayé, sa wò ó, ó wà ni júujùu, o si ______; ati ọrun, imọlẹ̀ kò si lara rẹ̀, Mo bojuwo gbogbo òkè nlá, sa wò ó, o warìrì ati gbogbo òkè kekeré mì jẹ̀jẹ̀, Mo bojuwo, sa wò ó, kò sí ènìyàn kan, pẹlupẹlu gbogbo ẹyẹ oju-ọrun sa lọ, Mo bojuwo, sa wò ó, Karmeli di aginjù, ati gbogbo _____ rẹ̀ li o wó lulẹ̀, niwajú OLUWA ati niwájú ibinu rẹ̀ gbígbóná.
**Jeremiah 25:33**
Awọn ti OLUWA _______ yio wà li ọjọ́ náà lati ipẹkun kinni ayé títí de ipẹkun keji ayé, a kì yio sọ̀fọ̀ wọn, a kì yio kó wọn jọpọ̀, bẹ́ẹ̀ni a kì yio sin wọn, nwọn o di àtàn lori ilẹ̀.

Àkíyèsí: Gbogbo ayé yio di piparun nipaṣẹ ilẹ̀-ríri ati ìjì òjò-dídì ni yio ṣẹlẹ̀ ni ìpadabọ̀ Jesu lẹ̀ẹkeji. Ayé yio sì di òkùnkùn biribiri. Awọn òkú yio wà yíká gbogbo ojú ilẹ̀ ayé, laisí ọ̀fọ̀, nitori kò ni si ẹnikankan ti yio wà lááyè mọ́. Awọn olododo yio wà ni ọrun, ati awọn ẹni buburú nì yio kú. (Wo àfikún ti o wípé “Ọgbun ainisalẹ̀”)

**5.** Nibo ni awọn àyànfẹ́ yio wà ni ìgbà ẹgbẹ̀rún ọdun náà, kinni wọn yio ma ṣe?

**Johannu 14:3**
Bi mo ba si lọ ipèsè àyè silẹ fun nyin, emi o tún padà wá, emi o si mu nyin lọ sọ́dọ̀ emi tikarami; pé _______ emi gbé ______, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu.
**Ifihan 20:4**
Mo si ri awọn ìtẹ́, nwọn si joko lori wọn, a si fi _______ fun wọn: mo si ri ọkàn awọn ti a ti bẹ́ lori nitori ẹrí Jesu, ati nitori ọ̀rọ̀ Ọlọrun, ati awọn ti kò si foribalẹ fun ẹranko náà, ati fun aworan rẹ̀, tabi ti kò si gbà àmì rẹ̀ ni iwaju wọn ati li ọwọ́ wọn; nwọn si wà laaye, nwọn si jọba pẹlu Kristi li ẹgbẹrun ọdún.
**1 Korinti 6:2,3**
Ẹnyin kò ha mọ̀ pe awọn _____________ ni yio ṣe idajọ ayé? Njẹ́ bi o ba ṣepe a ó tipasẹ nyin ṣe idajọ ayé, ẹnyin ha ṣe alaiyẹ lati se idajọ awọn ọ̀ran ti o kere julọ? Ẹ kò mọ̀ pé awa ni yio ṣe idajọ awọn angẹli? Melomelo li ohun ti iṣe ti ayé yi?

Àkíyèsí: Ni ìgbà ẹgbẹ̀rún ọdun náà, awọn ènìyàn mímọ́ yio wà li ọrun lati ma ṣe idajọ. Awọn kọ́ ni yio sọ iye awọn ti a gbàlà tabi awọn ti wọn nù, nitori Ọlọrun ti se èyí funrara Rẹ̀. Awọn ni yio fi ìdí idajọ Ọlọrun mulẹ̀. “nitori a ti fi idajọ rẹ̀ hàn.” Ifihan 15:4. Idajọ Ọlọrun tó yẹ fun awọn tó nù li a o fi ìdí rẹ mulẹ̀, bẹ́ẹ̀ni awọn èrè fun awọn olododo ni a o fi fun wọn (Ifihan 22:11,12). Àkókò idajọ́ yi jẹ́ anfaani fun awọn ènìyàn mímọ́. Fun apẹẹrẹ, kí a ṣọ wípé iwọ de ọrun, o sì ni anfaani lati mọ̀ pé pasitọ rẹ ti o fẹ́ràn kò sí nibẹ̀ - sibẹ̀ awọn ìgárá ọlọ́sà wà nibẹ̀! Ó dájú pé wa a fẹ́ lati gbọ́ àlàyé ohun to ṣẹlẹ̀ to fi ri bẹ́ẹ̀. Awọn angẹli yio fi ìwé ohun ti o ti ṣẹlẹ̀ hàn wá lati yanjú gbogbo iyèméjì. Ni akókò idajọ́ yi, gbogbo ènìyàn yio ti gba ti òdodo, ìfẹ́ ati aisoju-saajú èniyàn ti Ọlọrun gbọ́. Wọn o sọ pé “Nitori òtítọ́ ati òdodo ni idajọ́ rẹ̀.” Ifihan 19:2. (Lọ wo akori afikún "Àwòrán ẹgbẹrun ọdun.")

**6.** Kinni yio ṣẹlẹ̀ ni opin ẹgbẹ̀rún ọdun náà?

**Sakariah 14:1,4,5,9**
Kiyesi i, ọjọ́ OLUWA mbọ̀, a o si pin ikogun rẹ laarin rẹ, Ẹsẹ̀ rẹ̀ yio si dúró li ọjọ́ naa lori ______ ______ , ti o wà niwaju Jerusalẹmu ni ila-oorun, òkè Olifi yio si _____ meji si ihà ila-oorun ati si ihà iwọ̀-

oorun, afonifoji nlánlá yio wà: idajì òkè naa yio sì sí sihà ariwá, ati idajì rẹ̀ siha gusu, Ẹnyin o si sá si afonifoji òkè mi wọnni: nitori pé afonifoji òkè naa yio de Asali; nitootọ, ẹnyin o sa bi ẹ ti sa fun isẹ̀lẹ̀ ni li ọjọ́ Ussiah ọba Juda: OLUWA Ọlọrun mi yio si wá, ati gbogbo awọn ẹni-mímọ́ pẹlu rẹ, OLUWA yio si jọba lori gbogbo ayé: li ọjọ́ naa ni OLUWA kan yio wà, orukọ rẹ̀ yio si jẹ ọkan.

**Ifihan 21:2**
Mo si ri ilú mìmọ́ nì, Jerusalẹmu titun nti _______ _______ lati ọdọ Ọlọrun wá, ti a mura silẹ bi iyàwo ti a ṣe lọṣọ fun ọkọ rẹ̀.

Àkíyèsí: Ni òpin ẹgbẹ̀rún ọdun náà, Jerusalẹmu titun pẹlu awọn ènìyàn mímọ́ ninu rẹ̀ yio ti ọrun sọkalẹ sí orí-òkè ti a mọ̀ si Olifi bayi. Oluwa yio si mu kí awọn òkè náà tẹ́ bi òrí-ilẹ̀.

**7.** Kinni yio tún sẹlẹ̀ lati tu Satani silẹ̀ kúrò ninu túbú rẹ̀ ?
**Ifihan 20:5,7**
Awọn ______ iyokù kò wà laaye mọ́ títí ẹgbẹ̀rún ọdun naa yio fi pé. Eyi li ajinde ekinni, Nigbati ẹgbẹ̀rún ọdun náà ba si pé, a o tú Satani _______ kúrò ninu túbú rẹ̀.

Àkíyèsí: Lẹhin ti awọn ẹni búburú ba ti jinde tan, a o tú Satani silẹ̀ lẹẹkan si, kí o le tan wọn jẹ, yio sì tún ma a dari wọn.

**8.** Kinni Satani yio se nigabti a ba ji awọn ẹni búburú dìde tán ?
**Ifihan 20:8,9**
Yio si jade lọ lati maa _______ awọn orlẹ-èdè ti mbẹ ni igun mẹrẹrin ayé jẹ, Gogu ati Magogu, lati gbá wọn jọ si ogun: awọn ti iye wọn dabi iyanrìn òkun, Nwọn sì gòkè lọ la ibú ayé já, nwọn si _______ ibudo awọn ènìyàn mímọ́ ká ati ilu àyànfẹ́ náà; iná si ti ọrun sọkalẹ wá, o sì jo wọn run.

Àkíyèsí: Satani yio ma tan awọn ènìyàn jẹ, pé kò yẹ ki wọn le oun kúrò ni ọrun, yio si tun wi fun wọn pé ki awọn jọ yi ilú náà ká, pé awọn yio borí ilú náà, awọn yio si di alaṣẹ lori ilú náà. Nigbati awọn enìyàn búburú náà ba rò ó pé, wọn kò jẹ ki awọn pẹlu wọle si Jerusalẹmu titun náà, awọn náà yio mura lati dojukọ ati lati borí ilú náà.

**9.** Nígbàtí gbogbo rẹ ba le tán, kinni yio dá gbogbo rẹ̀ duró ?
**Ifihan 20:11,12**
Mo sì rí _______ _______ nlá kan, ati ẹniti o joko lori rẹ̀, niwájú ẹniti ayé ati ọrun fò lọ; a kò si ri àyè fun wọn mọ́, Mo si ri awọn òkú, ati ewe ati àgbà, nwọn dúró niwájú ìtẹ́; a sì sí awọn ìwé silẹ, a sì sí ìwé miran kan silẹ ti iṣe ìwé ìyè: a si ṣe _______ fun awọn òkú lati inu ohun ti a ti kọ sinu awọn ìwé naa, gẹ́gẹ́ bi iṣẹ́ wọn.

Àkíyèsí: Lojiji ni ìtẹ́ Ọlọrun yio déédé hàn lókè ìlú náà, bẹ́ẹ̀ naa ni àkókò idajọ́ tó gbẹ̀hìn yio bẹ̀rẹ̀. Gbogbo òfin to wà lori ìlú Ọlọrun ni a o mu kúrò lẹṣẹkẹṣẹ. A o sì sí awọn ìwé, ohun gbogbo yio si di mímọ̀ fun awọn ẹni búburú ati olododo (Luku 12:2,3).

**10.** Kinni yio sẹlẹ̀ lẹhin ti a ba ti dá awọn ẹni búburú lẹ́jọ́ tán?
**Romu 14:11**
Nitori a ti kọ ọ pé, Oluwa wípé, Bi emi ti wà, _______ eékún ni yio _______ fun mi, ati gbogbo ahọ́n ni yio si jẹ́wọ́ fun Ọlọrun.
**Fillipi 2:10,11**
Pé, li orukọ Jesu ni ki gbogbo eékún ki o maa kúnlẹ̀, awọn ẹniti mbẹ li ọrun, ati awọn ẹniti mbẹ ni ilẹ̀, ati awọn ẹniti mbẹ nisàlẹ̀ ilẹ̀, Ati pé ki gbogbo ahọn ki o maa _______ pé, _______ Kristi ni Oluwa, fun ogo Ọlọrun Baba.



**Ifihan 19:1,2**
Lẹhin nkan wọnyi mo gbọ́ ohùn nla li ọrun bi ẹnipe ti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn, nwipe Halleluiah; ti Oluwa Ọlọrun wa ni ìgbàlà, ati ogo, ati ọlá ati agbara: Nitori otitọ ati _________ ni _________ rẹ̀; nitori o ti ṣe idajọ àgbèrè nla nì, ti o fi àgbèrè rẹ̀ ba ilẹ ayé jẹ́, o si ti gbẹsan ẹ̀jẹ̀ awọn iranṣẹ́ rẹ̀ lọ́wọ́ rẹ̀.

Àkíyèsí: Gbogbo awọn ẹni búburú ni yio gbà wípé Ọlọrun ti gbìyànjú lati gba awọn lọwọ́ iparun, ṣùgbọ́n awọn ni awọn kọ̀ lati gba ìrànlọ́wọ́ Ọlọrun ti O ran si àwọn, ti àwọn si tẹsiwajú lati ma a gbe ninu ẹ̀ṣẹ̀. Lẹhin ti gbogbo eniyàn ba ti gbọ ẹri yi tán, rògbòdìyàn ẹ̀ṣẹ̀ yio di ìgbàgbé pátápátá, ààyè yio sì sí sílẹ̀ lati pa awọn ẹlẹ́ṣẹ̀ run.

**11.** Kinni yio tún sẹlẹ̀ ?
**Ifihan 20:9**
Nwọn si gòkè lọ la ibú ayé já, nwọn si yi ibudo awọn eniyàn mímọ́ ká ati ìlú àyànfẹ́ naa; _______ si ti ọrun sọkalẹ wá, o si ______ wọn run.
**Ifihan 20:15**
Bi a ba si ri ẹnikẹni tí a kò kọ orukọ rẹ̀ sinu ìwé ìyè, a sọ ọ́ sinú _______ iná.

Àkíyèsí: Iná Ọlọrun yio sọkalẹ wa si orí awọn ẹni búburú ati adagún iná yíká ìlú Ọlọrun. Iná náà yio si sọ wọn di eérú (Malaki 4:3). Eṣu ki yio ní agbára lori iná yi, ti a npè ni ọrun apadi. Dipò bẹ́ẹ̀, eṣu ati awọn angẹli rẹ̀ ni a o ma dá lóró ninu iná náà, wọn yio sì di eérú (Ifihan 20:10; Esekieli 28:18). Kò sí ajinde kúrò ninu iná yi, èyí ti a npè ni ikú kejì (Ifihan 20:14).

**12.** Lẹhin ti iná náà ba ti kú, kinni Ọlọrun yio ṣe fun awọn enìyàn Rẹ̀?
**Isaiah 65:17**
Sa wò ó, emi o ______ ọrun titun ati ayé titun: a kì yio rántí awọn ti iṣaaju, bẹ́ẹ̀ni nwọn kì yio wá si àyà.
**2 Peteru 3:13**
Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bi ileri rẹ̀, awa nreti awọn ọrun titun ati ayé titun, ninu eyiti_________ ngbé.

Àkíyèsí: Lẹhin ìgbèkùn aadọrin ọdun ti Babiloni, awọn ọmọ Isreali padà wá si ilẹ̀ ileri wọn, wọn sì tún ìlú wọn kọ́. Lẹhin ẹgbẹrun ọdún náà, awọn enìyàn yio ri Jesu bi o se dá ọrun titun (òfurufú) ati ayé titun tí o pé, nibiti ẹ̀ṣẹ̀ kò ti lè gbérí mọ́ (Nahumu 1:9). Paradise ti Adamu ati Efa ti sọnù nipasẹ ẹ̀ṣẹ̀ ni a o dá padà pẹlu gbogbo ogo Edẹni rẹ̀. Alaafia, ayọ̀, ìfẹ́ ati ìdùnnú pípé ni awọn enìyàn Ọlọrun yio ni títí lai.

**13.** Nibo ni Ọlọrun ati awọn olododo yio pàpà má a gbé?
**Ifihan 21:3**
Mo si gbọ́ ohùn nla kan lati orí ìtẹ́ nì wá, nwipe, Kiyesi i, àgọ́ Ọlọrun wà pẹlu awọn ènìyàn, oun ó sì maa ba wọn _______, nwọn o sì maa jẹ ènìyàn rẹ̀, ati Ọlọrun tikararẹ̀ yio wà pẹlu wọn, yio si maa jẹ́ Ọlọrun wọn.
**Matteu 5:5**
Alabukún-fun li awọn ọlọ́kàn tútù: nitori nwọn o jogún _______.

Àkíyèsí: Ọlọrun Baba ati Ọlọrun ọmọ ni yio gbé pẹlu awọn ẹni mímọ́ Rẹ̀ ni ayé titun. Ronú si i - ki o ni Ọlọrun bi alajọgbé!



# Èsì Rẹ

Jesu wípé, "Mo nlọ pèsè àyè sílẹ̀ fun nyin." Johannu 14:2. Jesu ní ibùgbé kan fun ọ, ni ìlú mímọ́. Se o fẹ́ gba ẹ̀bùn ìyè ainipẹkun Rẹ̀, ki Ó le fún ọ ní ìbí titun, ati pé ki Ó tún mura rẹ sílẹ̀ fún ijọba Rẹ̀.

ÌDÁHÙN:______________________

# Àfikún

Ipele yìí yio fun wa ni awọn ìròhìn kíkún lati tún kẹkọ síwájú.

## Àwòrán ẹgbẹ̀rún ọdún náà

### Ìṣẹ̀lẹ̀ ti yio bẹ̀rẹ̀ ẹgbẹ̀rún ọdun náà

1. Jesu yio padà wa fun awọn ẹni mímọ́ Rẹ̀, ati awọn òkú olododo yio jinde.
2. Awọn ẹni búburú yio di pípa nígbà bíbọ̀ Jesu, pẹlu ilẹ̀ rírí ti o lagbara ati òjò dídì.
3. A o pa awọn olododo lára dà, wọn o sì pàdé Oluwa ni ofurufu.
4. Ofurufú yio si gbé awọn olododo lọ si ọrun.

### Ẹgbẹ̀rún ọdun

Ipò àti ìṣẹ̀lẹ̀ ti yio ṣẹlẹ̀ ni ìgbà ẹgbẹ̀rún ọdun náà.

1. Awọn ẹni mímọ́ ní ọ̀run nkópa ninu siṣe ìdájọ́ awọn ẹni búburú.
2. A fi ipá mu Satani ati awọn angẹli rẹ̀ lati wà ninu òkùnkùn biribiri ninu ayé.
3. Kò sí ẹ̀dá alàáyè láyé mọ́.

### Ìṣẹ̀lẹ̀ ti yio parí ẹgbẹ̀rún ọdun náà:

1. Jesu padà wa pẹlu awọn ẹni mímọ́ Rẹ̀, ati ìlú mímọ́ nì sọkalẹ si ori-òkè Olifi.
2. Awọn ẹni búburú ji dide, Satani si tan awọn ẹni búburú nì lati lọ kọjú ìjà si ilú-mímọ́ nì.
3. A da awọn ẹni búburú lẹ́jọ́, a jẹ wọn níyà iná ti o sọkalẹ lati ọrun lati jó awọn ti o nù.
4. Ọlọrun dá ọrun ati ayé titun lori eérú ayé ti a ti yà sí mímọ́.

## Ọ̀gbun Àìnísàlẹ̀

Ọ̀rọ̀ yi "ọ̀gbun àìnísàlẹ̀" lati inu ìwé Ifihan 20:1 ni a ma nsì túmọ̀. A tumọ̀ rẹ lati inú èdè Giriki "abusosi." Ninu majẹmu lailai ti Giriki, a lo ọ̀rọ̀ yi lati fi pe ohun tí o sofo, ayé ti o sokùnkùn ki a to dá a. "Ayé sì wà ní jújúú, o si ṣofo; òkùnkùn si wà lójú ibú: Ẹ̀mí Ọlọrun si nrábàbà lójú omi." Genesisi 1:1,2. Ọ̀rọ̀ yi "abusosi" li a tún lò ninu ìwé Luku 8:31 lati sọ nipa bi ipò ti ẹmi eṣu kò ba ti ni ààyè ṣe ma nrí.

Li àkókò ẹgbẹ̀rún ọdun náà, eṣu yio wà ni dídè pẹlu ipinnu pé "ki o má baa tan awọn orilẹ̀-èdè jẹ mọ́." Ifihan 20:3. Ìdè ti ara kò le ṣe é de ẹ̀mí. Ohun kan ni yio di eṣu lọwọ́ lati ma tan awọn ènìyàn jẹ, ohun kan naa ni pe bi ko ba si ènìyàn láyé mọ́! Nígbàtí Jesu ba dé, a o pa gbogbo awọn ẹni búburú ṣùgbọ́n awọn olododo ni a o mu lọ si ọrun, nigbana ni Satani ati awọn angẹli rẹ̀ yio wà ni dídè ninu ayé yi, ti wọn kò si ni lee tan ẹnikẹni jẹ. Fun ẹgbẹ̀rún ọdun wọn yio ma rìn kaakiri lati ma a wo iṣẹ ọ̀tẹ̀ wọn. Ni ọ̀nà yi ni a o gbà de eṣu ati awọn angẹli rẹ̀. "A o si ko wọn jọ pọ̀, bi a iti kó ara tubu jọ sinu ihò, a o ti wọn sinú tubu, lẹhin ọjọ pupọ̀ li a o si bẹ̀ wọn wò." Isaiah 24:22.

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP12.indd 2 12/7/12 9:42 AM